**Akiyesi**

Anfę Eniti yio ma ba wa ta Iwe Irohin Imolę. Ni agbegbe Ilorin tabi Ilumiran. E lo si odo Ogbeni :- A. O. AJIBOYE Esq. Ni Oja Gambari Ilorin

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**OWE**

Aiso ehin ika. Ni a nfi owo bo o. Bi a ba fa agbo fun egungun Ayun e je orogan. Ki wo koloye agunmate. Olowo kole jo orogan. Ki iwo fa joye agunmate.

VOL. III No. 132 MONDAY J.NUARY 11 — JANUARY 17 1960 KOBO KAN (1d)


# Olopa mu meji ninu awon Olori Osise ni Loko

EKO. Ninu osu to koja lo yi ni, ijogbon be sile ni ogba Loko, larin m e j i awon Osise Loko na ati Oga won Agba pata-pata.

Sir Ralf Emerson ti o nse Alaga ati Olotu gbogbo Ile ise Reluwe. Ohun ti asigbo wipe o fa ede koyede na wa ni wipe, awon Osise Loko sope nigbati aseko to lati fi ise Reluwe ti Ile Naijiria sile, ni Ogbeni Emerson se gba isinmi lo si Ilu re. Bi o ba si lo be, oni lati joko si ohun ni, ki nwon si fi'elomiran ranse gegebi Olotu ise Reluwe.

Sugbon nigbati Ogbeni Emerson gba isinmi na lo ilu re, kaka ki n w o n fi elomiran ranse, on kanna os tun pada wa. Nigbati awon egbe osise si sakiyesi oro yi nwon so fun wipe awon ko le ba sise nitori iwa re ko te awon lorun.

A gbo wipe ese ti Ogbeni Emerson ma gbe lehin na wipe, gbogbo awon ti o je pataki larin awon egbe osise, ni nwon ngbe lo silu miran lo sise.

Awon enia meji ninu egbe awon osise ti owo awon olopa te larapa rogbo-diyan ti won da sile nitori oro yi ni Ogbeni S. O. Oduleye ti o je Sekitieri tabi Akowe egbe na a t i igbakeji Akowe egbe na Ogbeni E. N. O. Otti.

Awon Olopa seleri wipe o si ku awon enia bi marun si, ti awon yio mu wa fun igbejo nitori jo oro yi.

## Awon Asofin Agba

Awon Omo Egbe Ile Asofin ti Ipinle Iwo Orun, ti o je N.C.N.C jade kuro ni ibi ipade ile A ofin ati ti Loba-loba ti ase papo ni ojo Jimoh, nigbati Igbimo mejeji fe fi ase si 'yan awon agba Asofin ti I j o b a Apapo (Senators)

Oruko awon agba Asofin ti Ipinle Iwo Orun na niyi Ogbeni Olajide Somolu fun Abe-okuta. O l o y e Sanni Esangbedo ati Dalton Asemota fun Benin. O l o y e Solomon Nupowu su, f u n Ikeja ati Epe (Colony Area Ogbeni M. G. Ejaife f u n Ijaw. Oloye Iya-Afin Wuraola Esan ati Ogbeni E. A. Lagunju. fun Ibadan. Oloye T.A Odutola fun Ijebu O l o y e J. S. Olayeye ati Ogbeni:-

P. A. Ogundipe fun Ondo. Ogbeni S.A. Eyitayo ati Dokita J.O. Omitowoju fun Oyo awon ti ipinle ila orun ni ogbeni H. Ileloh Dokita E. Esin O g b e n i P.C. Ndu J.K. Nzerem Ilmoh. Oloye Ezogo R.A Patria Dokita N w a f o r I.Acholun a t i L.C. Obi ti Ipinle Ariwa Hassaniyola Turaki Alhaji Abubaka Garba. Henry O. Abaagu Zauna Medalia S h e r i f Abelusalani Yusuf, Alhaji Muhammad Sani Ungogo Hausa, Rafindadi Abubakar, Bale Bawe Maleke Muhammadu Sani, ati Nuhn Banali.

EKO. Oba Adele Oloye Fagbenro Beyioku Oloye Bayo Doherty ati okan ninu awon Oloye Oni fila fifun ti a ko ti yan.


## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ero Alata todaraju gbogbo eyi ti won ti nlo telerilo leyin ata lilo o tun le lo Igbado ati Oka Baba ati Ewa - ere orisirisi.

**£45 Ni a nta** Pelu Enjinni Petrol tabi ati pelu Eletiriki Muto.

O WA NI SOBU:-

**Akoshile Brothers,**

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 2139 5. LAGOS.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO




MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ta se ni Asepe fun Awon omode, ati nlo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise ribiribi ti o ti nse. MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara pupo fun igbona iko, otutu Aipeti, Osi inu omode, jedi j e d i Kokoro ori omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu ki omode ma nsun fonfon, o nmu ki ehin hihu je iro run fun awon omode, osi ojeki awon omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon omode. Ijafara lewu pupo, tete lo ra ti e ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re je 2/6d Igo nla je 4/6d
**LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo**

*Wholesale Distributers*

**A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

| | |
|---|---|
| 6, Balogun Street West | 34, Docemo Street |
| Lagos Nigeria. | Lagos |
| Phone 22515 | Phone 204247 |

**IMOLE**

EJIN ORO WA:-
IMOLE DE OKUNKUN
PARADA
*Editorial Works & Office*
16, Bamgbose Street,
Lagos.
Telephone:- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,

## Kabo Ololá Macmillan

NI ORUKO GBOGBO AWON ENIA NAIJIRA IWE "IROHIN IMOLE" KI OLOLA HAROLD MACMILLAN OLOTU IJOBA GEESI TI YIO DE SI ILE WA, ni irole oni ni agogo marun.

Tayotayo ati tifetife ni a o fi gba o si ilu wa, a lero wipe wa gbadun gbigbe re ni arin wa, atipe ibewo re yio tun di gbanyingbovin okun ore ti o wa larin ati tiwa.

Ibewo re mu wa ranti ibewo oba binrin Gesi Elizabeth keji ni odun 1956 ati ti iyekan re ni 1958 ati ti Aburo baba re omoba Glou-cester ni odun 1959 tokoja Ibewo wonyi fihan gbangba pe ore nla ti okun re yi ni o wa larin ile Gesi ati Naijiria, a si lero wipe ko leja.

Sugbon oro kan ewe ni o ye ki a fi ye ara wa, eyi yi si ni ti ero etu oloro ti (Atomic Bomb) Faranse ore Gesi fe ju sile ni ibuso bi ogorun mesan si ilu wa ti o si le pa wa lara.

Gbogbo enia lo mo bi etu Oloro yi ti loro si ati bi oti nse Jamba si, nitorina ale so fun Ololá Macmillan pe ko je didun inu wa, ona ti Ijoba re fi owo mo oro na a ko fe ki Faranse dan etu yi wo, nitori a mo ewu ti o wa ni di re, o si dawa loju pe ti Ijoba Gesi ti Macmillan je olotu re ba ba wa mu oro na ni gidi, Faranse ati dekun didan Etu yi wo. A mo pe o wa ninu agbara Ijoba Gesi lati da Faranse duro, sugbon won ko ni se be nitori ki ise Oyinbo ni wa, yio je didun inu wa, yio si je ohun ti yio tun mu okun ore ti o wa larin wa tun di ghanyin-gbanyin ti Ololá Macmillan ba le lo ipo re lati dekun Faranse ki won ma dan etu oloro yi wo ni Sahara.

Lekan si a ki o ni oruko gbogbo enia Naijiria kabo, Ololá Harold Macmillan, o ku wa lojú pe wa gbadun gbigbe re larin wa titi iwo yio fi lo.

## Ijoba yan awon Ara Eko meji to nlo si Igbimo. (Senate)

Awon enia meji ti Ijoba yan si Igbimo Senate, ni Ogbeni Fagbenro Beyioku, ati Ogbeni Bayo Doherty. Eniti otun nlo si Igbimo Senate na pelu ni Alaiyeluwa Oba Adele Keji ati, okan ninu awon Ijoye Ilu, sugbon akoiti mo eniti awon Ijoye ilu yio yan si igbimo Senate, nitoripe ode koyede wa larin nwon.

Ogbeni Mayaki so wipe ninu ipade ti nwon se ninu Igbimo ti nwon lo se nilu Oyinbo, ninu odun 1957, a so nibe wipe ki awon enia meji se Asoju fun Ilu Eko ati nigbati nwon si ma yan awon enia meji na si igbimo Senate, eyini Fagbenro Beyioku ati Ogbeni Bayo Doherty.

Awon enia nwonyi lo si pa ohun po yan awon enia meji na si Igbimo, awon ni Malam Ribadu. Ogbeni F. S. Macween, ati Ogbeni Lawson ti o je Olori awon Alatako, Igbimo Lagos-Town Council.

Igbimo na ni ipade lojo Atalata tise Ojo karun osu January. 1960.

## Adetona di Oba Awujale Ijebu-Ode

Omoba Sikiru Kayode Adetona, eni odun merin

WO OJU EWE KETA



Advert No. 2.

## Federal Elections 1959

It has been discovered that through an error in the taking down of results over the telephone, the results for Constituencies 64. Igala North East, 66. Igala South and 67. Igala North West were incorrectly given, the figures for the successful candidate and the next candidate being transposed in each case The results for these Constituencies are as follows:-

64. IGALA NORTH EAST.

Peter Ochimana Tkoula. Igala Union/N.P.C. 15,432.
Andrew Ochani Ekele. Igala Divisional Union/N.P.C 4,485
Alfa Okoliko Andrew. Action Group. 805.
Abdul Alhaji. N. E. P. U. 545.

66. IGALA SOUTH.

Daniel Obaje Enefola. Igala Union/N. P. C. 11,799
Benjamin Alewo Obaje. Igala Divisional Union/N. P. C. 5,969.
Ahmadu Gbobe. N. E. P. U. 1,768.
Sule Opaluwa. Action Group 1,225

67. IGALA NORTH WEST.

James Ankita Yacim. Igala Union/N.P.C. 13,157.
Jacob Akun Olokun. Igala Div. Union/N.P.C. 5,249.
Umaru Amedu. Action Group. 962.
Joseph Atabo Chibabi. N. E. P. U. 673.

This correction to the announcement of the results does not affect the state of the parties since in each Constituency both the successful candidate and the next candidate are in alliance with the N. P. C.

J. J Warren
*Secretary,*
Electoral Commission

din logbon, ti o si je a keko ni ilu oynibo tele n i Ijoba ipinle Iwo orun nijiria t i gba gegebi awujale Ijebu Ode, lehin iku Oba Daniel Adesanya, eni ti o wo aja ni odun to koja.

Omoba Adetona pada si nijiria lati ilu O y i b o n i November odun to koja lehin igba ti awon Afoba je ti yan a, g e g e b i Awujale.

Awujale titun yi n i Omode ju larin awon mefa t,i idile Anikilaya gbe jadel ati joba, nitori Idile won l o y e kan.

Nigbati agbo pe won yano moba Adetona jade ni September odun, ti o koja opolopo ninu awon ebi Idile re n i o ti a ke kori pe awon ko gba, won si pe ejo ni ile ejo giga ti Abeokuta, pe ki i l e ejo di Ijoba lowo gbigiba Adetona ni oba. Ejo na si wa ni ile ejo d i lowo-lowo yi.

Sugbon nisinyi, imura ati ipalemo ti wa lati gbe Ade lori Omoba Sikiru Kayode Adetona gegebi Awujale Ijebu-Ode a t i oba gbogbo Ijebu.

### Osoba yio jejo ni Assize

Ogbeni P.J. Osoba ti a fi esun pe oji maun din ogoji egbeuu poun owo le yowo pawo onisowo (Merchants Bank) ni adaji ile ejo Ogbeni Crane ni on fi ejo re si Assize ni osu keta opuu ni (March)

Ogbeni Osoba ti nse ejo yi lati odun to koja, Ogbeni Oloye Moore si ni agbeoro re. Ile ejo gba iduro re fun egberun mewa poun Ogbeni Osoba ko lati soro ni ile ejo kekere osi fi eri ile ejo nla re c (Assize)


ṢORA FUN

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA